

# EYI NI ỌJỌ AWỌN ỌJA ILẸ WA.

### ỌJỌ AJE 8TH OCTOBER (MONDAY)

| Ilu | Oruko Awon Oja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe rẹ | Mushin. |
| Abẹokuta | Owode Otta Abalabi Sodeke Omida Ilawo Owowo Obafemi |
| Ibadan | Oja-Oje |
| Ijebu | Ikenne Okun-Owa Erunwon Omu, Ago-Iwoye |
| Ijesha | Ijebu-Ijesha Jene Itagu Odogbo, Iloko, Ipetu, Owode, Idoko, |
| Ondo ati Eti Odo | Agbabu Igbogi Ishua Erinketa |
| Egbado | Olorunda, Kajola Ilobi Erede |
| Ogbomosho | Araromi. Iregba |
| Ekiti | Erekesan |
| Ibinni | |
| Delta | |
| Igbajo | Iloro |

### ỌJỌ ISẸGUN 9TH OCTOBER (TUESDAY)

| Ilu | Oruko Awon Oja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe rẹ | Agege Ikeja. Ebute-Ero, Ojo Ajido |
| Abẹokuta. | Lafenwa Obada Oba Kajola Ajegunle, Idogo, Ogumaki, Itori |
| Ibadan | Ibuko Lalupon |
| Ijebu | Ibefun. Atikori, Imushin, Ago-Iwoye Ijesha-Ijebu, Isara, Imodi, Mamu |
| Ijesha | Esa-Oke. Iware. Ejioro. Odo Ibokun, Esa-Odo, Ijeda. Ikeji. |
| Ondo ati Eti Odo | Igbo-Egunren, Atijere. Oni Ebiwo. |
| Egbado | Idi-Emi Ibeshe Lasilo Atta Oko |
| Ogbomosho | |
| Ekiti | Ifaki Okemesi |
| Ibinni | Uromi. |
| Delta | |
| Igbajo | |

### ỌJỌ 'BỌ 10TH OCTOBER (WEDNESDAY)

| Ilu | Oruko Awon Oja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe rẹ | Oyingbo |
| Abẹokuta. | Ijoko, Iberekodo, Asu, Wasimi. |
| Ibadan | Olode. Ogunjana, Lagun. |
| Ijebu | Aiyepe. Sagamu Ita-osu Ogere Irolu, Ita-Iloti, Itele, Oyingbo, |
| Ijesha | Ijebu-Ijesha. Ibodi. Ibode Kajola, Oluwa'da |
| Ondo ati Eti Odo | Abigi. Aiyetoro. Oka. Ilara. Epe. |
| Egbado | Alagba Ilaro. Sunwa. Iboro. |
| Ogbomosho | Obada, Gambari |
| Ekiti | Ilogbo. Oke-Aiyedun. Idogun Eke. |
| Ibinni | |
| Delta | |
| Igbajo | |

### ỌJỌ 'RU 11TH OCTOBER (THURSDAY)

| Ilu | Oruko Awon Oja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe rẹ | Obun-Eko |
| Abẹokuta. | Atan, Agbado, Ifo, Itoku Isabo, Odeda, Ibara. |
| Ibadan | Ijaiye-Orile Iresi Obada Egbeda. Oyedeji |
| Ijebu | Ilishan, Odogbolu, Atan, Imope Ishan, Isara, Imodi, Akesan |
| Ijesha | Ilase Epe Iloba Iperindo. Imuroko, Erinmo, Esa-Oke. |
| Ondo ati Eti Odo | Agirifon-Ilutitun, Odojomo, Igbotako, Ileoluji, Obunkekere. |
| Egbado | Aiyetoro Tata Randu. Ado-Odo |
| Ogbomosho | Iresa-Du, Arolu. Egbeda Jabata, Oke Imale |
| Ekiti | Egosi. Odo-Aiyedun |
| Ibinni | |
| Delta | Kokori |
| Igbajo | |

### ỌJỌ ẸTI 12TH OCTOBER (FRIDAY)

| Ilu | Oruko Awon Oja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe rẹ | Mushin. Badagry |
| Abẹokuta | Otta, Abalabi, Sodeke, Owode. Omida Ilawo Owowo Obafemi |
| Ibadan | Oja-Oje |
| Ijebu | Ikenne Okemowa Erunwon Omu, Ago-Iwoye |
| Ijesha | Ijebu-Ijesha, Oyu, Itagu, Idoko Iloko, Odogbo, Owode, Ita Apa |
| Ondo ati Eti Odo | Ishua. Aye. Erinketa. Agbana Igbogi |
| Egbado | Ilobi. Igbogila. Ijoun Imasai |
| Ogbomosho | Araromi Iregbo |
| Ekiti | Erekesan |
| Ibinni | |
| Delta | |
| Igbajo | Iloro. |

### ỌJỌ ABAMẸTA 13TH OCTOBER (SATURDAY)

| Ilu | Oruko Awon Oja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe rẹ | Agege, Ikeja |
| Abẹokuta. | Lafenwa Obada Oba Kajola Ajegunle, Idogo, Ogumaki |
| Ibadan | Lalupon, Ibuko |
| Ijebu | Isara, Imodi, Ibefun, Atikori, Imushin, Ijesha-Ijebu, Mamu Ijesha-Ijebu |
| Ijesha | Esa Oke Iwara Ejioro Odo Ibokun, Esa-Odo |
| Ondo ati Eti Ondo | Igbo-Egunren |
| Egbado | Idi-Omi Lasilo Igan-Okoto, Atta Oko |
| Ogbomosho | |
| Ekiti | Ifaki Okemesi |
| Ibinni | Uromi. |
| Delta | |
| Igbajo | |

### ỌJỌ AIKU 14TH OCTOBER (SUNDAY)

| Ilu | Oruko Awon Oja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe rẹ | Oyingbo. Ejinrin. |
| Abẹokuta. | Ijoko. Iberekodo, Asu. Wasimi. |
| Ibadan | Ogunjana, Lagun, Sagbe, Olode |
| Ijebu | Aiyepe. Sagamu Ilisan Ogere, Irolu, Itele, Ita-Iloti, Ora |
| Ijesha | Ijebu-Ijesha. Ibodi Ibode. Kajola, Oluwa'da. |
| Ondo ati Eti Odo | Oka. Ilara, Abigi, Aiyetoro, Epe. |
| Egbado | Alagba. Ilaro Sunwa. Iboro. Jigga |
| Ogbomosho | Obada, Gambari. |
| Ekiti | Ilogbo, Oke-Aiyedun, Idogun Eka. |
| Ibinni | |
| Delta | |
| Igbajo | |

### ỌJỌ AJE 15TH OCTOBER (MONDAY)

| Ilu | Oruko Awon Oja |
|---|---|
| Eko ati agbegbe rẹ | Ogun Eko |
| Abẹokuta. | Atan Agbado Ifo Itoku. Isabo Odeda, Ibara, Itori |
| Ibadan | Ijaiye-Orile. Iresi Obada Egbeda. Oyedeji |
| Ijebu | Ilishan. Odogbolu, Atan. Imope. Ishan, Isara, Imodi. Ajegunle |
| Ijesha | Esa-Oke Ilase Epe Iloba Iperindo, Imuroko, Erinmo. |
| Ondo ati Eti Odo | Odojomo. Igbotako. Ileoluji. Obunkekere. Agirifon-Ilutitun |
| Egbado | Aiyetoro, Tata. Randu, Ado-Odo |
| Ogbomosho | Iresa-Du. Arolu. Egbeda |
| Ekiti | Egosi. Odo-Aiyedun. |
| Ibinni | |
| Delta | Kokori. |
| Igbajo | |

## ITUMỌ ALỌ

1. Igi-ope.
2. Igi-[illegible].
3. Awon ti o [illegible] popo [illegible].
4. Omo-[illegible] ati [illegible].
5. Agbara-ojo, [illegible] ati ere.
6. Afefe [illegible].
7. Oja.
8. Eka-ere.
9. Oku.
10. Agbara-ojo.

## Adaeke ji dide ninu oku

ENUGU.

IYANU nla ni o je fun awon ore ati awon alabakedun ebi Adaeke, arabinrin kekere kan ni ilu Akagbe, itosi mejo si Enugu, nigbati arabinrin na (Adaeke) ti nwon ro pe o ti ku, ti nwon si kan oku re sinu posi, bere si ja giddi-giddi ninu posi na bi nwon ti ngbe e lo sin ni ojo Eti ti ise ojo kerinla osu ti o koja yi.

Lesekese ni nwon si posi na, nwon si ba a nibe ti ngbe fuke-fuke. Nwon tete mu u lo si ile re nibiti o gbe nfi igbadun sayo lati igbana titi di bi a ti nko iwe yi.


EYIN ABIYAMO ẸKU ORIIRE! EGBOGI AGBONOLA YI DE!




EGBOGI AGBONOLA

EKUNDAYO MEDICINE STORES 41, VICTORIA ST. LAGOS.

ILERA MI TI O DARA



L'arọ

ANDREWS

Iwọ paapa  le fo pẹlu OWO-PỌỌKU

by W·A·A·C WEST AFRICAN AIRWAYS CORPORATION





"FUN EGBOGI" ki o si jẹki awọn ọlọja gba koko rẹ

"MAṢE FUN EGBOGI" arun korikori yio gba koko rẹ dipo




ARUN KORIKORI NI ỌTA RẸ NI GBOGBO AKOKO OJO

"PERENOX" ATI "PEREPOD"

NI AWỌN OHUN IJA RẸ

Ma a lo wọn DEDE ki o si dabobo awọn koko ati owo rẹ

O wa kakiri ẹka ile iṣẹ ati iọdọ awọn aṣoju

THE CO-OPERATIVE SUPPLY ASSOCIATION

ati

THE UNITED AFRICA COMPANY

Plant Protection Ltd.


# BI IPILẸ BA BAJẸ

*Lati oju ewe kẹta*

Ipin ninu Banki na gẹgẹ bi iwe adehun ti nwọn ti ṣe. Ọgbẹni Ojike gba pe nitotọ adehun ti duro saju ọjọ karun oṣu karun ọdun na.

Ojike tun sọ pe on ba Dokita Mbanugo sọrọ nipa owo na ki Igbimọ to ṣe ipade ni ọjọ kefa oṣu kẹrin ọdun. Nigbati Ọgbẹni Mackenna bi Ọgbẹni Ojike lere pe kini ṣe ti o sọ lẹkan pe on ko ba Dokita Mbanugo sọrọ nipa owo na, Ojike dahun pe "idamu lo ṣemi".

## Kele gbe iwe aṣiri Ojike

Nigbati ọrọ ka Ọgbẹni Ojike lara, o so pe gbogbo awọn ẹlẹgbẹ on alakoso iṣẹ Ijọba mọ nipa ọran na bi o tilẹ jẹ pe nwọn ko joko papọ sọ nipa rẹ ninu Ipade Igbimọ Alaṣẹ Ijọba. Ojike ko le sọ bi nwọn ti ṣe mọ, iyẹn nipe on ko lo sọ fun wọn, ṣugbọn on mọ pe Igbimọ ti ngmojuto Eto Inawo lo ṣe iwe ikede si iwe irohin nipa rẹ. Ọgbẹni Mackenna fi han Ojike ninu iwe akọsilẹ Igbimọ na pe ko si apere pe Igbimọ na ṣe ikede rara. Ojike sọ pe bẹni.

Ninu nwọn nsọ eyi, Ọgbẹni Mackenna bere lọwọ Ojike bi iwe-aṣiri (diary) rẹ ba wa nitosi. Ojike tọwọ bọ apo rẹ, o si fa iwe aṣiri rẹ ti ọdun to koja jade, ṣugbọn ko fẹ fi i silẹ laigba imoran lati ọdọ Loya rẹ. Kawi-kafo, Alaga Iko Iwadi na fi kele gbe iwe na mọ o lọwọ, o si di eyi ti Iko Iwadi ati awọn agbẹjọro gbogbo yio ka lakagba lati mọ bi Ojike ti rin nipa ọran nla na. Alaga ṣeleri pe ohun to ba jẹ mọ ọran na nikan ti nwọn ba ri ninu iwe aṣiri na, ni nwọn yio sọ fun araiye gbọ. O dabi enipe, egburu fẹ fa egburu jade.

## Azikiwe ko ṣai lọwọ nibẹ

Lati oju ewe kini

Dokita Azikiwe ni ẹniti o ṣe e. O ṣe alaye bi Dokita Azikiwe ti ṣe ni ọwọ si i pe ki nwọn gba Ọgbẹni A. K. Blankson ni Olotu-agba banki na, ati pe ki Dokita na ti ṣe kọwe si Ọgbẹni Blankson nipa aye rẹ na pe fun asiko ti on (Dokita Azikiwe) ba si wa ni Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ila-Orun ni Ọgbẹni Blankson yio fi wa ni aye Olotu-agba na gẹgẹbi aṣoju on.


## CLASSIFIED ADVERTISMENTS

NOW ON SALE:

ALAFIA ki o ma ba wa gbe 1957 Calendar ti a fi aworan ti Queen ati Oba Adele of Lagos … Doz. Postage extra. Apply I. Eho … Idita Street, Lagos.

KERE O! KERE O!! KERE O!!!

AWA nsọ … a … ti … o dara … fi o … ni … o baje … E. O. … and Sons, Box 193, ALKOSE.


Printed and Published by the Amalgamated Press (of Nigeria) Ltd. … Street Lagos. Editorial and Advert offices … Fun Owo-Irohin Yoruba … Chapel Street, Lagos.

# Gomina-Agba bọ Alaiyeluwa Ọba Adele Keji lọwọ


AWON OGBOLOGBO

(SCRAP)

OJE (LEAD)

IDE (BRASS)

BABA (COPPER)

AWON ALORU IRIN

ERO MOTO (RADIATORS)

PRANU EYO (ALLUMINIUM)

JE OWO

Ko wọn wa ta fun

BUCK (NIGERIA) LTD.,




# ỌDẸBIYI NSỌRỌ IWURI





Sofon' di Baba Ibeji

## Igbimọ Igbo-Ẹtiti jẹbi afọwọra


LUXURIOUS COMFORT....



VANGUARD III

UTC MOTOR DEPARTMENT

LAGOS
APAPA
IBADAN
ENUGU
KANO

Irora ati Arẹ-ara ti lọ

NIPA LILO EGBOGI IPARA

SLOAN'S



EGBOGI SLOAN NIPA IRORA

Surf O Titun! Onidan ni!

nfọ awọn aṣọ pẹlu agbara idan!



Bi o ba fi "Surf" fọ aṣọ wa ri bi eri o ti jẹ ma a jade ninu rẹ


O MỌ KEDERE KÒ SI NI ERI
Mobil
Sunflower
Kerosine
...O ti pẹ ti ati nlo o
o si jẹ epo Oyinbo ti
a nlo julọ ni Naijiria.
Kò ni idọti,
A si mã jo geregere
laini efin.
Mobil Oil Nigeria Limited

# Adotalelegbefa Egbe Alakuko d'Egbe Olope

IBADAN.

NI ojo Eti ti ise ojo kerinla osu yi ni Egbe Afenifere (Action Group) se ipade nla kan ni Kudeti, ni adugbo Ogbeni Adelabu. Ninu ipade na ni edegbeta (500) enia ti o ti je omo Egbe Alakuko (NCNC) teletele ti di omo Egbe Olope ti nwon si fi oruko sile ninu Egbe Afenifere (Action Group).

Ni ojo Abameta ti ise ojo kedogun osu yi kanna ni adotadinlegberin (750) enia ti o ti je omo Egbe Alakuko (NCNC) telert tun ya wo inu Egbe Olope sa pe, awon ti fi ara mo Egbe Afenifere (Action Group) ni Popo Yemaja ni Ibadan. Ogbeni A. M. A. Akinloye ti o je Alaga Ten Egbe Afenifere (Action Group) Ibadan si ko iwe-eri fun olukuluku egbe won le Alaga budo-egbe won lowo lototo.

## ISINKU IBIYEMI GA L'OLA

IGBOGILA.

L'OJO kedogbon osu ti o koja yi ni iya rere, Ibiyemi Asunle Olakilo fi aiye sile nigbati o di eni odun mejileladofa (112 years old). Mama yi je omo Olakilo, iran kerin nino Oniyi ti o te Igbogila do.

Awon omo oku yi po tobe tee ti iran kerin ninu awon omo re fi ba won se inawo isinku na. Awon omo oloku ma na wabi-wusi owo, malu meta ni nwon pa, oti ko ni 'ye. Opolopo enia ni o wa si ibi isinku na lati Eko, Ibadan, Abeokuta ati Addo.

## Oyin-momo Baba Egbe nf'ado s'obe

OSHOGBO.

NI ojo Aiku ti ise ojo kerindinlogun osu kesan odun yi ni Ogbeni Julius Ade. Egbedun, Baba Egbe Olomope African Church, se ase nlanla fun awon omo egbe re na fun ajoye ikore ti nwon se ni Ile Olorun na.

Baba egbe yi na owo, o si fi jije ati mimu te gbogbo awon omo egbe re lorun. K'Olorun fi opo odun na han wa o. Amin.



Ogbeni A. Okusaga, Minista Ilera ni Ipinle Iwo-Orun ti o wa ni owo otun ninu aworan yi, o nba Ogbeni A. Simpson Gbakeji Olori agba Ibi-ise Marine soro ninu oko "M.L. [illegible], okan ninu oko oju-omi ti nwon fi nsise nlanla ti nwon' ranse fun lati ilu Oyinbo.

* * * *

## Ogbomoso Parapo Oke-Oya fe se Ipade

NI ojo Aje ti ise ojo kokandinlogbon osu yi ni awon Egbe Ogbomoso Parapo Oke-Oya (Northern Region) yio bere ipade gbogbogboo ni Kafanchan, a si ni ireti pe gbogbo Egbe omo Ogbomoso ni yio ran asoju won wa.

Ninu awon eto pataki ti ipade na yio se, "Ilosiwaju ilu Ogbomoso yio je okan nibe". Awon ti yio si wa ba ipade na soro ni awon Oloye S. L. Akintola, Olola J. Adigun ati Olola Dipe.

Bi enikeni ba si ni imoran kan ti yio ko sowo si ipade na ki o tete fi sowo si akowe Ogbomoso Parapo Oke-Oya, Ogbeni D. A. Afegina P. O. Box 330, Jos. Ki Oluwa ki o so eni olukuluku omo egbe layo igbana o.

## IJO APOSTELI SE ODUN JUBILI

NI ojo keta osu kewa odun yi ni yio di odun medogbon (25 years) gbako ti Ijo Aposteli ti Kristi (Christ Apostolic Church) ti wo ilu Ikole. Awon ngbangba ati odo, lokunrin, ati lobirin si ti mura giri-giri lati se odun ajoyo yi pelu iyiri.

Opolopo awon enia ma yio si ti ilu okere wa lati Ekiti, Ilesha, Oyo, Ibadan, Eko, Ishan, Akoko, Owo, Ondo ati beebee.

A dupe lowo Olorun pe bi a ti ngbeeru gegebi Ijo beni a si tun ndagba ninu imo ati ore-ofe Olorun. Enyin Ijo C.M.S. ati Katoliki, mo ki nyin pe e ku aboye. Enyin Ijo Aposteli, mo ki nyin pe e ku-ori'rea. Baba egbe Ijo, e ku akomora. Ifaiyaran ati suuru. Enyin alagba ko laije nigba ti nyin. Enyin odo, e fi apere awon agba se arikogbon. Ire a kari o.

Jubili kenke, Jubili.



Ninu aworan yi yi o ri awon enia pataki meran ti awon ara ibile United States ni Washington pe fun ase apeje di nwon se fun Oloye J. A. O. Odebiyi, Minista Eto Eko Ipinle Iwo-Orun Naijiria ninu osu ti o koja yi. O wa lori irin-ajo ni Amerika [illegible]. Oruko awon enia pataki na ni lati owo osi Dokita Bashman ti U.S. Information Agency. Oloye Odebiyi, Ogbeni [illegible], akowe pataki ti Ethiopian Embassy.

## EGBE ATUNLUSE IJOMU SE AJODUN

EKO.

IROHIN ko to amojuba ni ajodun odun karun ti Egbe Atunluse Ijomu "Ijomu Development Association" se ni Eko ni ojo Abameta ti ise ojo kedogbon osu kejo odun yi. Awon Ogbeni R. O. Ajikobi ati Karimu Adebayo ni o se itoju onje adidun ati oripope ati ti egbe na ti pese sile fun awon alabaseye ojo na awon Ogbeni A. Olowu, S. B. Agbabi, Sennusiu Aje ati James Afolabi ni ran won lowo. Ogbeni T. A. Awodeji se eto ijoko.

Alejo ati amuti ni awon fi ibe ati mimo se. Ijo ojo na bosipe o le yanan, irohin ko se afojuba ni. Lehinti Ogbeni Sule Atolagbe, Alaga ti dupe lowo Olorun ati fun gbogbo awon alabaseye ojo na han ni awon Ogbeni Salawu Ladimeji, M. Adekunle Gbonde ati J. J. O. Ogunremi Baba-egbe s'oro lorun.

Awon omoye egbe na ni awon bi awon Ogbeni Amusa Adebayo, Joseph Abegunri, Jacob Abolaji, Michael Adebanjo, J. A. Awodeji, Karimu Gbonde, Yesufu Adedoyin, Samuel Awodele ati Joseph Awolaiye se gbidugbudu ninu ile ojo na.

Ajeyi-sa-ajodun o.

"NOTICE TO ALL EMPLOYERS

Employment and Earnings Enquiry—September, 1956."

[illegible]

Northern Region — Kaduna, Kano, Jos, Zaria.

Eastern Region — Enugu, Aba, Onitsha, Abakaliki.

Western Region — Ibadan, [illegible]

Southern Cameroons — Buea.

Lagos — [illegible]

[illegible]

O ngmu omo - owo lagbara ati ilera nigbati o ba fe hu ehin



[illegible]



Ashton & Parsons Infants' Powders

